HU HAHA ! HU HAHA !! ESURUN - KUNRUN


AWOGBA Omode fun Gbi, Esi, Biba-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 11ä, Great Bridge St., LAGOS

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

U. T. C.
Serves YOU - WELL -

VOL. VII No. 444. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 3, 1955. KỌBỌ MEJI (2d.)

## HU HAHA ! HU HAHA !! ESURUN - KURUN.

O ta si wa leti fẹrẹn wipe awọn alaşẹ ere ẹyọ ogbe'ro lati fi Ẹyọ Adamu - Orişa şe iyẹsi fun Alaiyeluwa Ẹni - Ọ'la Nla Ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi pẹlu ọlọ'la ọkọ rẹ ti nwọn yio fi ọ'la wọn bẹ ilu Eko wa yi wo ninu ọdun 1956, ti o mbọ yi.

Ọjọ na nku perewe nisisiyi ki gbogbo ẹnyin ọkawe wa fi oju s'ọna ati ri iran aladun na wo, nitoripe ere Ẹyọ Adamuorişa ki işe ere ọdọdun, akanşe ere pataki ni.

Ni apakan iwe Irohin wa yi ni ẹ o ri aworan Ẹyọ Adamuorişa ti a tẹ fun anfani ẹnyin ọkawe wa.

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 42/6d Now 32/6d
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
10A, Moloney Bridge St.,
LAGOS

## OLOYE ẸGBA MẸTA YỌ KURO NINU ẸGBẸ ALAKUKỌ.

ABẸOKUTA : Awọn oloye ẹgba mẹta ni nwọn yọ kuro ninu ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) Oloye Jinadu Dasaolu, Osi Igbore, Adeniji, Ọtun Badu Igbore, ati Jona han Ẹrinoşo Delu, Ogboye Igbore, ni nwọn ti yọwọ - y'ẹsẹ kuro ninu Ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn si faramọ ẹgbẹ - Afẹnifẹre (Action Group.)

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ọna tara ti enia legba lati di onişowo nilẹ Nigeria wa.
ni ile ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Ẹnikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ
aimọye awọn onişowo ilẹ Nigeria lara.
yala lati ma ta ọja fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa
ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IŞẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AŞOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Alaiyeluwa Ọba Obinrin Ilu Oyinbo

Aworan inu Iwe wa yi niti Arọmamọ Alaiyeluwa Ọba Obinrin Ilu Oyinbo Gẹsi ti gbogbo ilẹ Nigeria nşe ipalẹmọ lati gba ni alejo to yẹ fun iru ipo Ọba - nla rẹ papa ilu Eko ti wa yi ti o jẹ olu (olori) fun gbogbo ilẹ Nigeria.

Eleru a sun'gi l'ọjọ na, ki Edumare da ẹmi wa si ati alafia ara.





## Alaiyeluwa Ọba Adele, Keji.

AFINJU ỌBA T'O NF'OLA RERA.

A ni ireti wipe yio jẹ inudidun fun ẹnyin ọkawe wa lati gbọ wipe ọba wa, Adeniji Adele, Keji, ti ẹ nwo aworan rẹ ninu iwe wa yi ti fi aşẹ si wipe ki a şe ere ẹyọ Adamuorişa fi şe ẹyẹ fun Ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi ti o mbọ wa bẹ ilu Eko wa wo ni ọdun 1956 ti ao bọsi ni ọjọ mejidinlọgbọn oni.

## AJỌDUN KỌKANLELỌGỌRIN ỌGBẸNI CHURCHILL

Ọlọla Winston Churchill ti aworan rẹ mbẹ ninu iwe wa yi ni ẹniti o d'agba di ọmọ-ọdun mọkanlelọgọrin.

Ni ọjọ Wednesday ti işe ọgbọnjọ oşu November, 1955 ni o şe ajọyọ ọjọ ibi rẹ na, Ọba Obinrin ati Alakoso Ijọba ilu Oyinbo Gẹsi ranşẹ ki ku Ori're.



## Oye Otun Egba Di Ijongbon Ni Abeokuta.

A gbọ wipe oye Ọtun Ẹgba ti ilu Abẹokuta, ti awọn Igbimọ alabojuto Ofin ati aṣa ibilẹ ti Igbimọ Ibilẹ ilu Abẹokuta mu ẹnikan fun aye na, ti di ohun to fa atako lati ọdọ awọn ara Ilugun ati Ikereku nilu Abẹokuta.

Wọn ṣe atako wọn lori wipe ẹniti awọn Igbimọ mu na ki iṣe ara ilu Ilugun, beni ki iṣe ọmọ ilu Ikereku, ọmọ ilu Ikija ni iṣe, eyi ko si le rọgbọ nwọn igbati oye yi ti jẹ ohun ajogunba, Ilugun ati Ikereku, ti ko kan ilu Ikija gẹgẹ bi aṣa ibilẹ itẹhinwa, nwọn si tun sọ wipe ko si itan ilu Abẹokuta to faramọ iru aṣa bẹ.

Dẹẹdẹẹ mirahọ, bi ọrọ awọn Egun, ohun ti a ba fi ẹsọ mu ki ibajẹ, ohun ti a ba fi agbara mu ni ini'ni l'ara. Ẹ fi ẹsọ ṣe o.

## Gedegbe l'Eko Wa, Abo nyin Re O!

Awọn Yoruba ionpowe wipe, bi a ko ba pa iji ban iji ẹru ko mba iji. Ọgkẹu Ọlọ a Awolọwọ ti mọ ibiti nwọn nse ọrọ bọ, ki o to sọ wipe ki a pa ilu Eko pọ mọ ilẹ Yoruba yoku lori ti Ṣugbọn awa gẹgẹbi ara Eko, ase ni a taku nwọnle wipe, rara!

Bi a ba pa Eko pọ mọ ilẹ Yoruba yoku, awọn ajeji enia ko ni ri aye towọ bọ wa nidi, bẹni, aye Olori (Capital) ko ni kuro ni Eko.

Nisisiyi ọrọ na delẹ ẹnyin ti ẹ sọ pe Gedegbe l'Eko wa, ti ẹ fi ikanju ia ọbẹ gbigbona ti ẹ lọ yan awọn Kogledc ati ajeji si igbimọ, nigbati awọn gbe iwa wọn de fun nyin eṣe ti ẹ ko le ke lọ ba awọn ti ẹ yan si igbimọ.

(Wo yoku loju ewe kejọ)




## IKU MU ENI'RE LO



### James Ademosu

Aworan inu iwe yi niti ologbe James Ademosu Anperi, ti o ṣalaisi ni ile rẹ, 28, Idoluwo Street, l'Eko, nigbati o di ọmọ - ọdun mejileladọrin ni ọjọ ori rẹ.

Titi di ọjọ ti o fi aiye silẹ, on ni Alakoso ati Oludasilẹ ẹgbẹ Atunluṣe ọmọ Aiyepe, ati ẹgbẹ Ilọsiwaju ẹsin Igbagbọ.

Ologbe na fi ọmọ mẹfa si aiye, onişowo pataki ni iṣe, o si tun jẹ Oniburẹdi atata ; ninu Ile - Isin Holy Trinity ni Ebute - Ero ni o ti sami Igbagbọ, ti o si di pataki ninu agbo Olugbala Kristi.

Awọn to wa sibi isinku rẹ ni awọn ẹnibi :- Ọgbẹni Dadi Owoaje, Kansilọ A. F. A. Dada, L. J. Dosunmu, Ọgbẹni Coker ati iyawo rẹ, J. A. Ogunmọdẹde, Alatimeji, Aṣoju Oloye Obiri, Ogunbẹkun Ajaloke, Shaii, Ojuri, Isikalu Odubanjọ, awọn ẹbi lati Aiyepe, K. Shobajọ ati awọn ẹbi, awọn aşoju ẹbi Anperi ti Ọgbẹni J. A. Odupitan jẹ Olori wọn, ọlọla Ọlayẹmi Tọbun, N. A. Amao, ati N. Ade. Kasunmu.

Iku pa Olowo bi ẹniti ko ni owo, iku pa Oniṣegun bi ẹniti ko ni ogun, iku pa Alufa bi ẹniti ko nke pe Allah, iku pa James Ademosu Anperi ẹni're.

Ọrun rere! Ọrun rere!! Ọrun rere!!!

## Ipade Awon Babalawo Ni Ibadan

Ipade awọn Babalawo ti ilẹ Nigeria ti nwọn ma nşe ni oşu mẹtamẹta yio wa ni ile Araba Ibadan ni Ọjọbọ (Thursday) ọjọ kejọ oşu December, 1955, ni agogo mẹwa owurọ.

Awọn Babalawo ti awọn ilu ti a darukọ wọnyi yio yan aşoju wa si ipade na. Oloye Ajanako, Araba Eko, yio yan aşoju rẹ wa, Ilu Eko yio yan aşoju, Abẹokuta, Ibadan, Ẹdẹ, Oshogbo, Ile - Ifẹ, Gbọngan, Ikorodu, Shagamu, Ijẹbu - Ode, Ode - Rẹmọ, Ile - Igbo, Agbọwa, Iwo, Ikire, Ode - Omu, Ọgbagba, Oshun, Agberi, Ishara, Ipẹtu - Modu, Modakẹkẹ, Akinlabi, Ara, Telebu ati awọn ilu ti a kole darukọ tan.

Ipade ti nwọn şe kọja ni ilu Iragbiji ni arinrin tobẹgẹ ti ẹnikẹni gbadun rẹ, Ọba Iragbiji şe wọn ni alejo rẹpẹtẹ.

Awọn Babalawo ti ilu Ibadan nşe ipalẹmọ lati gba alejo ni agba - gbadun si Ilu Ibadan nisisiyi.

# Iku Ti Ko Ba Ni Pani, Yio Gbe Alawo Rere Ko Ni

Lati ọwọ Ẹṣọ Ikoyi

Nigba kan, ajalu buruku kan ṣẹlẹ ni ile Ifẹ Ọyẹlagbo. Aja'u na ni wipe bi ọba tabi Ọlọfin ba ku nigbani, Ab'ọbaku ọba na nilati fi aiye silẹ lọjọ ti Ọba baku.

Ni Ile Ifẹ Ọyẹlagbo, bi nwọn ba ti jẹ Oye Ọlọfin tan, nwọn nilati jẹ oye Amọfa. Eyi ni nwọn npe ni Ab'ọbaku nile Ọyọ.

O si ṣe lọjọ kan, Ọlọfin ṣe aisan titi de oju iku, o ru hanganran aṣẹhinwa, aṣẹhinbọ. Ọlọfin waja nwọn si pa Amọfa rẹ pẹlu. Nwọn tun jẹ oye Ọlọfin miran, nwọn si jẹ oye Amọfa fun u, ko lọjọ ko lọṣu Ọlọfin keji tun bẹrẹ aisan, oru arun ti o pa Ọlọfin kini lo pa Ọlọfin keji, bẹ-bẹ-bẹ, nigbti o di Ọlọfin kẹfa ti ẹkẹfa na bẹrẹ aisan, nigbana ni odu Ifa Idigbe wa fu s'oju ọpọn, nwọn bẹrẹ si kii bayi:-

> Amọ Ifa ma mọ ọna Ọffa, Amọ ọna Ọffa ma mọ Ifa, Adifa fun Ọlọfa kan ṣoṣo ti o ku ti o nrun arun igbo, nrun ọpẹrẹ nilẹ, Ekurẹ di aṣigba, a nibi Ọlọfa yi ba ku iwọ Amọfa ni ao pa si o. Am'ọfa gbọ, o sa wọ inu igbo lọ. Idigbe.

Nigbati Amọfa gbọ bi a ti ki Ifa yi tan, ẹru ba gidigidi, nitoripe o ti ri gẹgẹbi nwọn ti ṣe pa awọn Amọfa ti o ti ṣiwaju rẹ nitori na afara kosi, ki o to di wipe Ọlọfin kẹfa waja, o ti sa wọ inu igbo lọ.

Bi o ti nsalọ ninu igbẹ yi, bẹni o pade ọkunrin Ogboju-ọdẹ kan ti o ṣọdẹ erin titi ti o si sọnu sinu igbẹ. Amọfa fi ọna han a tan, o tun ko sinu igbo, o nsalọ. Bi o ti tun nsalọ bẹni o tun pade iya arugbo kan ti o ṣẹgi silẹ tan, ti ko le gberu, iyagba na bẹ Amọfa ki o jọwọ gbẹru on.

Ṣugbọn Amọfa dahun wipe, Jọwọ fi mi silẹ o jare, a ni Ọlọfin nku lọ, nwọn si nfẹ pa on si oku rẹ, nko ma roju lati gbe ru enia ninu eyiti mo wa yi o" Iya arugbo na wipe, bẹni iwọ sa duro gberu mi na, nitori emi da ndan ni iku na ti o ti npa gbogbo awọn Ọlọfin.

Nigbati Amọfa gbọ eyi o duro, o si ran iya arugbo na lẹru rẹ kọri sile, bi nwọn ti jumọ nlọ sile, Iya arugbo sọ fun wipe, bi o ba pada dele. sọ fun awọn ọmọ Ọlọfin ki nwọn gbẹ i'ẹ nibi akete busun Ọlọfin ni ibi ori, nibi aiya ati nibi ẹsẹ, nwọn o ri amu kọkan nibẹ, ti a ti gba ẹjẹ gbogbo awọn Ọlọfin si, ki a mu diẹ ninu ẹjẹ ti ori, ki a fi wọn ori Ọlọfin, ki a mu diẹ ninu ẹjẹ aiya ki a fi wọn aiya Ọlọfin, ki a mu diẹ ninu ẹjẹ ẹsẹ ki a fi wọn ẹsẹ Ọlọfin, nigba na, alafia yio de si Ọlọfin ko si ni ku mọ, ara rẹ yio bọ sipo.

Amọfa dupẹ gidigidi lọwọ obinrin na tan, o si kọri si ile. Ọba Ọlọfin ti ku ogedegede egungun, o sọ fun awọn ọmọ Ọlọfin gbogbo ohun ti iya arugbo na wi. Nwọn ṣe bẹ, nwọn si ba a gẹgẹ bi iya arugbo na ti sọ. Nwọn si ṣe gẹgẹbi iya na ti sọ nitotọ ara Ọlọfin bọ sipo, bẹni ko si ku mọ.

Amọ Ifa ma mọ ọna Ọffa, Amọ ọna Ọffa ma mọ Ifa. Adifa fun Ọlọfa kẹfa. To nra run igbo, nrarun ọpẹrẹ nilẹ. Ekurẹ d'asigba Ọlọfa kẹfa ko ku mọ. Idigbe,


**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT :

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Faji Market)
LAGOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfation are Guaranteed



## E S'AKIYESI

IGBADUN-OMODE
AWOGBA FUN ỌMỌDE



The Celebrated Fever Mixture and Infants' Preservative
Prevents Sickness, Cures Measles, Fevers, Gripes etc. etc.

Sole Proprietors
PHILIP GBENLE & BROTHERS
6 Balogun Street West
LAGOS NIGERIA

ORIKI IGBADUN ỌMỌDE

Njẹ o ti ra Igbadun Ọmọde fun ọmọ rẹ bi? Ogun pataki fun iwosan ọmọde.

Awo ọmọ bi Olodumare, ogun ti abiyamọ ko ri ti o nba ninu jẹ. Abiyamọ ri tan o ndunnu ; baba ọmọ bu s'ẹrin.

Igbadun ọmọde ti o ma nda Abiku ọmọ lẹkun anku. A fi gbogbo ile ṣe ọmọ wẹrẹ. Ko ṣe mani fun awọn Abiyamọ ni ogun igbadun ọmọde yi jẹ. Tete sare lọ ra igbadun ọmọde ki o bẹrẹ si lo fun ọmọ rẹ, ọmọ rẹ yio si gbadun.

24/- fun mejila (dozen.) 2/6d fun ọkan each.

LILO OGUN NA :-

Ṣibi imu tea kan lẹrinmẹta lojojumọ.

IṢẸ RẸ :-

Iba, ọrẹrẹ, igbona, ọka, aiperi, ehin hihu, ati oriṣiriṣi arun to ma nyọ awọn ọmọde lẹnu. Tọwo, iwọ yio si ri pe rere ni Igbadun ọmọde nṣe fun ọmọ rẹ.

Iwọ le ri ogun yi ra ni gbogbo Ṣọbu ti nwọn nta ogun ni Najiria.

Wholesale Distributor :-

PHILLIP GBENLE & BROTHERS,
6 & 11, Balogun Street West Lagos Nigeria


## E Fi Oruko Sile Fun Idibo Iwo-Orun

# Ministry Of Education Western Region

ISSUE OF TEACHER'S CERTIFICATES IN THE WESTERN REGION.

As a result of the constitutional change which took effect on 1st October 1954, the award of teachers certisficates of all grades has become, in the Western Region, the responsiblity of Ministry of Education. This means that teachers who qualify within the Region after that date will receive a Western Region Certificate authorised by the Honourable the Minister for Education.

2. There are however teachers who qualified before 1st October 1954 and who have not yet received their Certificates. Such teachers will be given the old form of certificate. As the Examination Branch of the Cheif Federal Adviser's office in Lagos has closed down, arraugement has been made for the certificates to be issued by the Ministry of Education Ibadan.

3. Application forms on which teachers can apply for their certificates will be distributed to all Provincial Education Offices and to Proprietors. These forms should be filled only by teachers who qualified BEFORE 1st October 1954 and are teaching in Western Region Schools. Teachers who qualified as a result of the 1954 examination need not apply. Their certificates will be issued as a matter of course.

4. Completed forms should be posted to the Director of Education Western Region, Examinations Branch, Ibadan to reach him between now and December 31st 1955. Applications received after his date will be discountenanced unless there is special reason.

# ELETI ỌFẸ

A-NJU WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ELETI - ỌFẸ LAGOS"
Phone 23379

VOL. VII NO. 444 LAGOS SATURDAY DEC 3, 1955.


## Ara Eko Fi Ete Sile Npa Lapalapa

Ni ẹnu ọjọ meta yi ni irohin ọkan-ko-jọ-kan nkan wa ba wa nipa fi ile wiwo nilu Eko. Irohin wọnyi njade ni oni uru bi aṣọ Eku gun, ṣugbọn eyi ti a fi oju ri nit awọn ọgọrọ obinrin ti wọn ko ara wọn jọ lati ṣe atako si Ijọba Eko wipe awọn ko fi aramọ eto ile wiwo yi.

Awa Eleti - Ọfẹ da muso ni ẹmẹta fun awọn obinrin wọnyi, fun isowọpọ ati if'ohunṣọkan wọn lati k'ẹdun l'ori ọrọ yi, ṣugbọn bi a ti fi iwe wa kin wọn l'ehin to, a ko fi aramọ ti ile Oloye Dokita Maja ati ile Ọba Alaiyeluwa Adeniji Adele, Keji, ti awọn obinrin wọnyi k'ọju ija wọn si.

IBITI OJO BA ṢU SI NI A NNA ADO SI.

A ko le fi ẹtẹ silẹ ki a ma pa lapalapa, gbogbo ẹnyin ọkawe wa ni ẹ mọ daju wipe aṣẹ ilu Eko ko si lọwọ awọn eni meji yi rara; awọn ti o ni aṣẹ Eko ni awọn Igbimọ apapọ ti a npe ni Council of Ministers ti o jẹpe ẹgbẹ N.C.N.C. (Alakukọ) ni ida rẹ wa ni ọwọ wọn pẹlu Gomina Agba.

KI AMA ṢE SỌ ỌRẸ D'ỌTA

Bi awọn obinrin wọnyi ba fẹ ṣe atako si irufe ofin kobakungbe bayi nigba miran, o yẹ ki nwọn mọ amọdaju wipe ọrẹ wọn ni Oloye Dokita Maja ati Alaiyeluwa Adele Keji. Koyẹ ki a ṣe aimore si awọn eniti ti nfẹni to si nwa rere wa.

EDEGBE L'EKO WA, GBAMGBA L'EKO WA

Awọn Yoruba mọnimọni ni o pa owe yi, "Bi ọmọde ba ṣubu, a wo iwaju, bi agbalagba ba ṣubu, ẹhin ni iwo," ati wipe "Ọpa agbele'ka ti ẹhin l'oju." Eyi ni ero wa ti a fi ṣe ikede fun ẹnyin ọkawe wa wipe ki ẹ maṣe jẹki Eko yọ kuro ni ẹkun Iwọ-Orun, nitoripe a ti mọ ibiti afẹfẹ na nfẹ si. Abọ re o!


ABOKI



TI IWULO RE LOKIKI
yika Nigeria

SOSEMANI lo je fun ilekile
Fun orisirisi AILERA, atara
Gbogbonse lo je.

RA IGO KAN LONI
nitori AJEBIDAN ni

LODO

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES
Amunigun Street, Phone 189x, Box 295, Ibadan.


## Itumo Awon Oye Ile Yoruba

Arẹ - Oye yi jẹ agba Oye fun Alafin Ọyọ, nitoripe a ko gbọ wipe Oye kan tun tayọ rẹ ayafi Alafin

Jagunna - Oye yi nigba atijọ jẹ oye awọn Onisunmọmi lati ṣiwaju lọ si oko sunmọmi.

Balogun-Baba-Ologun, tabi Aṣiwaju ogun lati ilu kan lọ si ilu keji.

Asipa - Aṣip dẹ, tabi ẹniti o kọkọ njade lati ṣe ohun kan nigbati oju gbogbo ọmọ awo ba pe.

Oluwo - Olori-Awo tabi aṣiwaju fun gbogbo awọn ọmọ Awo kan.

Akala - Awọn ọmọ awo yi ni o kọkọ ngbọ bi ijoye kan tabi enia pataki kan ba ku, Akala a gbe ọrun mọ.

Apena - A-pa-enia. Ẹnikẹni ti o ba jẹbi ẹṣẹ ipania, on ni ẹniti o laṣẹ lati pa Oluwa rẹ.

Giwa ede yi jẹ ti Hausa, ti nwọn fi npe Ajanaku, Olori ẹgbẹ ni a npe bẹ

Ọtun - Oye yi ni a fi npe ẹniti ipo rẹ fẹrẹ to ti Giwa

Osi - Oye yi ni a fi npe ẹniti ipo rẹ fẹrẹ to ti ọtun.

Iyalode - Iya-Olode. Oye yi ni a fi npe Iya Ọba, tabi obinrin ti ipo rẹ ga.

Erelu - Ere-Oluwo, tabi iya Oluwo

Ayawo - Aya-ọmọ-Awo.

## Oko Sa Iyawo O Si Pokunso

A gbọ wipe ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Gabriel Aluko fi ake kekere ṣa iyawo rẹ ti o njẹ Adewunmi Ezekiel ni ejika lẹba ọrun nigbati ọrọ kan ṣe bi ija larin wọn.

Nwọn ni nigbati ija yi bẹrẹ ti ẹ'ẹgiri yọ ake ti o bẹrẹ si ṣa iyawo rẹ ni Bale wọn (Onile ti nwọn ngbe) ba kl'gbe lọ sọ fun awọn ọlọpa ki ọlọpa to-de, jagun ti n'agbẹ bora. Awọn ọlọpa yara gbe iyawo to ṣa l'ọgbẹ lọsi ile Alaisan ni ko jẹ araiye ko jẹ ara-ọrun. Ni gbogbo oru Tuesday ni nwọn fi nwa ọkunrin na, ṣugbọn wọn ko ri, ni owurọ ọjọ Wednesday ni wọn to ri nibiti o pokunso ninu igbo lẹba ile iwe abule Agọ ni Ajegunle Apapa.

Iyawo mbẹ ni ile alaisan nisisiyi, oku Gabriel ni nwọn ri ninu igbo o.

## R. S. P. C. A. Eka Ti Nigeria-Eko

ỌSẸ ILERA FUN AWỌN ẸRAN ỌSIN — 1955.

AYẸWO AWỌN OJA

A ṣe ayẹwo ọja nilu Eko, lati ri awọn Isọ ohun ọsin ti awọn oluta awọn adiẹ tunṣe dara - dara Awọn enia pataki mẹta ni o ṣe ayẹwo na, a si fun awọn ti isọ wọn yege ni ẹbun fun itọju isọ awọn ohun ọsin. Awọn obinrin ti o gba ẹbun na niwọnyi:-

| | | | | Madam |
|---|---|---|---|---|
| 1. | Ọja Oyingbo | Isọ No. | 589. - | Wuriatu |
| 2. | Ọja Jankara - | „ „ | 7. - | Nusiratu |
| 3. | Ọja Sandgrouse | „ „ | 581 - | Abigail Kọmọlafẹ |
| 4. | „ „ | „ „ | 589 - | Muniratu Oshodi |

A. Jọsẹ Adeogun


IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

## Mo Yowo Kuro Ninu Egbe N. C. N. C.

Emi Sadakatu B. Abudu ti o ti nṣ̀ Igba kan ja fun Iloṣiwaju ẹgbẹ N. C. N.C ni agbegbe Ẹgun Awori, mo jẹwọ loni wipe emi ti yọwọ - yọsẹ kuro ninu ẹgbẹ N. C. N. C mo si ko t'apa - t'ẹsẹ mi sinu Ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Bi a *ko* ba mọ ibiti a nlọ ao mọ ibiti a ti mbọ wa. Idi rẹ ti mo fi yọwọ kuro ninu ẹgbẹ Alakukọ ni wipe gbogbo ileri ti nwọn ṣe fun wa, ko si eyiti nwọn muṣẹ lati ibẹrẹ 1950, a ko ri ohun pataki kan ti nwọn ṣe fun wa ṣugbọn awọn ẹgbẹ ọlọpẹ ndagba, nwọn nsanra, nwọn si nyọkun batakun. Ile ni a nwo, ki a to sọmọ l'orukọ.

## Ajibola D'oloye Ojora-Eko

Ni ọjọ ọsẹ (Sunday) ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu November, 1955, ni nwọn de fila Oye Ọjọra fun Ọgbẹni Ajibọla Lasisi Oloye Olumẹgbọn ni o de fila na fun u, ninu Iga rẹ.

Lẹhin fila dide na ni Oloye Ajibọla lọ si Oju Ọlọrun ni Great Bridge Street, nibiti o lọ ṣe ikansẹ gẹgẹbi aṣa ibilẹ fun awọn Oloye Eko. Lẹhin eyi ni o wa lọsi Iga Iduganran lati lọ juba fun Alaiyeluwa afinju Ọba Adeniji Adele, keji, ẹsẹ gbogbo awọn Oloye ni o pesibẹ, Ọba si sure fun u.

Nigbati o kuro ni Iga Idunganran, o di rẹrẹ ni Iga rẹ ni Ijọra l'ọna Apapa pẹlu ọpọ awọn enia pataki-pataki lẹhin rẹ nibẹ lọ'jọ na ohun jijẹ ati mimu pẹtirẹ.

Ki a maṣe gbagbe wipe Oloye Ọjọra tuntun yi ni o j'oye rọ'pọ Ọjọra Olughode Faro ti o ṣalaisi.

POLOWO ỌJA RẸ SINU IWE ATATA YI





ILE YI LI AWỌN AKẸKỌ NGBE NI ZARIA
(INSTITUTE OF ADMINISTRATION)

Ile yi, ti a kọ dara-dara jẹ apakan ilọsiwaju ninu idagbasoke ilẹ Hausa. Simẹnti Oyinbo Burham ṣe iranlọwọ pidigidi ninu kikọ ile na, ati awọn ile nla miran kakiri apa Iwọ-Orun ilẹ Africa. Niwọn adọdin ọdun sẹhin. Simẹnti Burham ti ṣe iranlọwọ li oriṣiriṣi ọna fun ilọsiwaju ilu nwọnyi. Eyi yi fi han wipe, simẹnti tirẹ ni o lagbara julọ ti a si le gbẹkẹle ni gbogbo aiye. Burham Portland Cement

BURHAM
PORTLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT CO. BURHAM WORKS PORTLAND CEMENT LONDON


E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun

# RESOLUTIONS ON THE CONSTITUTIONAL CONFERENCE

26th—29th OCTOBER, 1955.

At the Annual Regional Conference of the Action Group held in Ibadan on October 26th—29th, the conference, after considering the report of the committee on the 1956 Constitutional Conference resolve as follows :-

(1) That in accordance with the principle of true federalism residual powers should remain with the regions.

(2) That in order to promote the success of a federal constitution for Nigeria it is desirable to have more states provided that no region would be split into states unless there is a majority of the people wanting the separate state in the area concerned. There are sufficient resources in the area to support such state, and there shall be no fragmentation of existing ethnic units, and accordingly we support the creation of a Mid West State and of a Rivers, Ogoja, Calabar State.

(3) That the present method of appointing Ministers is unsound and that the Constitution be amended to enable the Governor-General to call on the leader of the party in the federal legislature who appears to him most likely able to do so, to form a government. In the opinion of this conference this proposed method will hasten the achievement of self-government for Nigeria.

(4) That there should be a senate at the centre consisting of equal representation from each region.

(5) That the Action Group delegation to the 1956 conference be empowered to prune the federal and concurrent lists as far as is compatible with the over-all interest of Nigeria and in particuilar to see that Police, Income Tax paid by non-Africans, Administration of estates, Antiquities, Insurance and sanctioning of Cinematograph films for exhibition be deleted from those lists.

(6) That Lagos should be re-incorporated in the Western Region.

(7) That a regional boundaries commission be set up under the constitution to examine and settle all claims for the re-drawing of boundaries between the regions.

(8) That revenue should be allocated on the basis of derivation compatible with meeting the reasonable needs of the Federal Government.

(9) That there should be self - government for Western Regional in 1956.

(10) That in view of Her Majesty's Government's decision at the 1953 Constitutional Conference in London the Action Group should do all that lies in its power to secure the agreement of the Northern Region to self-Government for the Federation of Nigeria.

## Orun Ati Egbin Ni Ibadan.

Olotu,

Jọwọ ṣe gafara fun mi lati sọ nipa t eri ati ẹgbin ti o wa ni ilu Ibadan, ti o si le fa arun buruku wọ ilu. Bi o ba ti de Oguepa ni ki o ma ṣe akiyesi ẹgbin ati eti lọtu ati losi titi de opopo Amunigun ati Agbeni nibi to je pe wọn nfi igbẹ se ọsọ s'oju titi. Kekere ni eyi, nigbati o ba oere si wo ojuto awọn ile Ibadan nse ni idin nse wọlọwọlọ yika ọpọlọpọ ile igbẹ wọn, ti gbogbo orun nbu si ilu yika.

O wa dabi eaipe ko si nkan to nje wole wole ni Ilu Bo ba bere lọwọ wole-wole, a ni ejọ Igbimọ Ibile Ibadan ni, Igbimọ a si ni ẹjọ wole - wole ni, awọn ẹlomiran a si ni ẹjọ awọn to gba iṣẹ na lọwọ Igbimọ ti wọn ngbowo ti wọn ko ṣiṣẹ ni. Katakata wọnyi ṣe ni wọn nbayi, bẹni orun buruku gba ilu kan Olubadan dakẹ awọn Ijoye ko fọ'hun bẹni ọgbẹni Adelabu ti iṣe Alaga Igbimọ ijọba Ibilẹ ko ṣe kini kan si ọrọ yi; bẹni gbogbo ilu nbu ti i fun orun buruku to le fa ajakalẹ arun wọlu yi papa ni asiko ẹrun bayi ti afẹgun nko eruku kakiri.

Dipo ki awọn alaimọtoto bẹru wole - wole, wole - wole lo njirẹbẹ fun wọn, idi rẹ awọn nikan lo ye. Ibadan ogoji ọdun sẹhin si tun wa san ju ti isisiyi lọ Lọna ilera ati imọtoto. Mo bẹ "Eleti - Ọfẹ" ko fi gege rẹ ji awọn ara Ibadan kuro ninu orun buruku yi, ki ohun to ṣe Eko nigba ti Prince of Wales ma ba ṣe Ibadan ni bibọ ti Ọba obinrin ilu Gẹsi mbọ wa bẹ wa wo yi.

Itiju pupọ ni pe Olu-ilu Ipinlẹ Iwọ Orun le wa ni iru ipo bayi pẹlu ogunlọgọ wole-wole ati awọn atunluṣe wọnyi, ki wọn ma si ri ọgbọn ti awọn le sa si iru ọrọ yi.

Bi a ba ranti pe ilu Ibadan pẹlu ọpọ enia inu rẹ ni o tobi ju ni ilẹ Afrika, a ko gbọdọ dakẹ lori iru ọrọ pataki bayi Abẹ Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olubadan ati awọn Ijoye rẹ Ọlọla Adelabu ati awọn Igbimọ rẹ ati gbogbo ọkunrin ati obinrin Ibadan ki wọn ba ni mojuto ọrọ aimọ ati ẹgbin ilu yi. Mo dupẹ o,

ỌMỌ ALA
IBADAN

## Iyawo Soja De Aja Si Loya.

Irohin ti a ri gbọ ni wipe obinrin oyinbo iyafin J. Edmonds ti ọkọ rẹ jẹ Saji ninu iṣẹ Ṣọja kan ni Surulere ni a gbọ wipe o dẹ aja rẹ si Lọya G. B. A. Coker nigbati Ọgbẹni Coker mu Wọn-'lẹ - wọn'lẹ lọ sibi ilẹ rẹ ti o wa l'ẹba ile wọn ni nọmba 22, Rotimi Street, Surulere.

Ohun ti o ya wa lenu ni wipe nwọn ni obinrin na sọ wipe on ni ifura si irin ọgbẹni Coker nitosi ile awọn ni o mu ki on ṣebẹ.

Adajọ fi ẹjọ na si ọjọ kẹfa oṣu January, 1956.


**Now Available**

BUGLES, BEDSTEADS, PAINTS, DISTEMPERS SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
and NEW COURT ROAD,
IBADAN



**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.
J.A.AJAO BROTHERS
Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos



**Polowo Oja Re Sinu Iwe Iroh in Eleti-Ofe**

## Irora Lakuregbe

Iwosan rẹ lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwosan ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe, o yẹ ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindinrin oluwa rẹ ko siṣẹ to, o nfẹ iranlọwọ. Nitori iru amodi bayi lati ṣe ṣegbogi DE WITTS, yio si fun enia ni igbadun ara.

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nṣe iwosan Lakuregbe, danwo, ki o lọ ra ọkan ni ṣọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba ṣiṣẹ tara, ṣugbọn bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio de si oluwa rẹ, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti ṣiṣẹ. Danwo lọ ra ni ṣọbu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles


## Irohin Ilu Oyinbo

IWE IROHIN ILẸ GẸSI SỌ WIPE IRIN AJO ỌBA OBINRIN ILẸ GẸSI SI NIGERIA YIO JASI RERE

Nigbati Iwe irohin kan ni ilẹ Gẹsi ti a npe ni "New Commmonwealth" sọrọ lori irin ajo ibẹwo ti ọba obinrin ilẹ Gẹsi ati ọkọ rẹ ti wọn yio ṣe wasi Nigeria ni ọdun ti o mbọ, o sọ wipe ayọ ati inu didun pupọ gbaa ni yio jẹ fun ilẹ Nigeria ti idagbasoke wọn npeleke nisisiyi, ti wọn si ti ni itara fun iru abẹwo bayi tipẹtipẹ. O ni, ajo ibẹwo yi ni yio kọ ẹ akọkọ ti ọba ilẹ Gẹsi yio ṣe wa si ilẹ iyanu yi. Ni bi ọgbọn ọdun sẹhin ni ọmọ ọba Wales kọ bẹ ibẹ wo ninu ẹrun geregere, lati igbana ibẹwo yi ti di itan.

Igbagbọ iwe irohin yi ni wipe irin ajo ọba ilẹ Gẹsi yi yio sọ ilẹ Nigeria di olokiki ati wipe ireti wa wipe awọn ilẹ miran ni apa iwọ-orun Africa yio ni iru anfani bayi ni aipẹ jọjọ.

WỌN DA ẸGBẸ ATỌWỌDA NI ILẸ GẸSI

Awọn ẹgbẹ titun kan ṣẹṣẹ dide ni ilu London nisisiyi; ohun ti wọn si nle ba ni lati ma ṣe orisirisi rọba fun lilo, lati ara awọn aloku taya ọkọ kẹkẹ ati awọn ohun elo miran. owo gọbọi ni wọn fẹ fi bẹrẹ eto yi. Awọn ẹgbẹ ti wọn ti gba lati da esu sinu eto titun na to mẹrin nisiyi, awọn ẹgbẹ wọnyi ni wọn nṣe awọn taya ọkọ ati kẹkẹ ti o pọju ni aiye Awọn miran ko ni pẹ ki ọwọ bọ iwe. Ipinnu wọn ni lati ṣe iwọn rọba bi ọkẹ meji ati abọ, wọn yio si bẹrẹ ni ọdun meji oni.

AṢỌ TI ILẸ GẸSI NTA FUN NIGERIA PẸLEKE SI I

Nigbati awọn igbimọ onisowo ilẹ Gẹsi ṣiro iṣẹ iriyu wọn ni aipẹ jọjọ, wọn ri. wipe aṣọ irun tabi aṣọ otutu ti awọn ta fun Nigeria titi di osu kesan ọdun yi ti ju gbogbo aṣọ ti awọn ta lakoko kana fun awọn jiẹ ti o wa ni apa Iwọ-orun Africa yoku lọ. Owo ti wọn pa lori aṣọ owu ti wọn ta nikan le ni ẹgbẹ heru lọrọ ọkẹ marun pọ... Ey ko si kan awọn ọja miran ti wọn tun pa o... g ...e ...e l ri.

## AGOGORO - EYO



Ere ẹyọ Adamuorisa jẹ ere pataki nilu Eko ti awọn ma nlo fun asiko pataki bi iru eyi ti o mbọ yi.

O jẹ ohun pataki idunnu fun wa lọpọlọpọ nigbati a gbọ wipe Ọgbeni M- B. Ogundairo ti iṣe Olori Ẹyọ ti fi iwo ikede si ode fun gbogbo enia ati awọn ile Olori ẹyọ Adamorisa bi Adimu, Oniko ati Ọlọgẹdẹ wipe ere ẹyọ yio wa ninu ọdun ti o mbọ yi, 1956.

Ati wipe ao sọ ọjọ ti ao ṣe ere ẹyọ na ganan laipẹ.

Ẹyin okawe wa yio ranti wipe a ṣe ere ẹyọ Adamorisa yi ni asiko ogun ajakaiye, 1918 ti wọn fi nkọrin bayi;-

"Onisẹmọ ye, Onisẹmọ jọwọ o, ko fun wa lowo sinku Oyinbo toku s'ogun o, oke rere ye ọmọba a nlọ ki Lugadi o" eyi jẹ asiko ti oloye Onisẹmọ igbana pa ipo da.

Yio jẹ ere aladun to yẹ fun Alaiyejuwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi ti o mbọ wa bẹ ilu wa wo ninu ọdun ti o mbọ yi l'agbara, Allah.


**Enjoy Your Own**
**—Songs—**



Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC is yours, on obtainable from :.

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers . . . .**
THROUGHOUT . . . . . . . . . . . . NIGERIA . .



## Efun ?i Eyi Tabi Edi ?

?IA MERIN KORUN APAPA-NDODO

EDE. Agbeyan irohin kan ti a gbo ni wipe okunrin kan ti oruko re nje Raji Ajani ti Agbo'le Ol-rin yo agende ni o ti de to ... ni dede ... me... s'e ojo Satide moju ojo ose to ... jagun ba be ... kuro l'orun ba ... re agbologba ti o nje Salawu, Adeyemju o si tun be egbon re ... eleyini o omo Ogota-odun, ti oruko re nje Rufai, so a

Nighati awon ara ile gbo igbe awon ti Raji Ajan be lori wonyi, ti ... re obinrin Q'ato de ... Orogun 'ya re Sad ta Ajea sare lo wo wipe ... ohun to de o, ori ... mej ni nwon ba nile ti o yi ninu agbara eje, enmo ki le'yi, nwon f'ese fee.

Oju ti Raji kan won, nse ni elegiri ... gba le won, o si l' awon me eji ba, oro- fa, Jagun t so ori mejeji k'ale en kan soso ninu awon ... re ti o ja ajoba lowo Raji Aj ni ni Alaratu Abeo t o si ... e arabinrin re, on ... en ti o ke lo ba awon olopa.

Kobumi Ademola Ogunkoya pelu opo opo olopa ... won lo mu Raji ti awon s ko awo o u lo si Ile Alaisan Oshogbo.

A g' o wipe nigbati nwon bi Kasi lere wipe kini fa iru eyi wa o dahun wipe nitoripe awon meretin ti on pa wonyi ni o ko iyawo on ti o fi ko on sile.

## KING'S COLLEGE, LAGOS

ENTRANCE AND SCHOLARSHIP EXAMINATION, 1956

The Entrance and Scholarship Examination for admission to King's College, in January, 1957, will be held on Saturday, March 24, 1956.

2. Candidates wishing to enter for this examination will receive application forms, particulars of scholarships and conditions of entry by carrying out the following instruction :

(i) Put your name and full postal address in BLOCK LETTERS on an empty, open foolscap envelope(a foolscap envelope measures 9 in. by 4in.)

(ii) Stick a 2d postage stamp in the top right-hand corner of this envelope.

(iii) Put the stamped, addressed envelope inside another addresed to:

THE OFFICER - IN-CHARGE OF EXAMINATIONS KING'S COLLEGE LAGOS.

and post it to reach him not later than 31st January, 1956. Application forms will NOT be sent to any candidate who does not carry out the above instructions exactly and no correspondence will be entered into about these. The Officers-in-Charge will NOT receive applications in person and will not interview any intending candidates.

3. The application form will give full instructions on the method of applying for entry to the examinations

4. Requests for forms will NOT be considered after 31st January, 1955, and completed application forms must reach the Officer-in-Charge NOT LATER than 28th February, 1956.

5. The examination will be held in Lagos Bamenda Beua, Kumba, Mamfe; Aba, Afikpo, Awka, Calabar, Ogoja, Okigwe, Onitsha, Owerri, Port Harcourt Umuahia, Uyo; Ilorin, Jos, Kano, Lokoja, Makurdi, Minna, Zaria; Abeokuta, Akure, Asaba, Benin City, Ibadan, Ijebu-Ode, Ilesha, Ondo and Warri.

6. Improper attempts to influence members of the College staff regarding the admission of any candidate will result in the disqualification of the candidates on behalf of whom the attempt is made.


## ARADAN NERVIGORA



Ogun eje pataki fun imarale agba ati aremo pipe fun awon alaya pupo. O dara fun inarun, eje d du, isokun oju, gbigbon owo, ailesun, ailokun ninu, ati irufe arun bawonni. O je ajidewe fun awon ti agbara won ndinku. On na yan ni okunrin yi lo ti o fi di "Afese kun bi ojo." 5/6d. pere pelu owo oko 1/6d. e.c. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores**

114, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta. phone 44153. A tun wa ni New Motor park (Ogunpa Ibadan).


## Iwe Ebe Si Oba Ilorin Nipa Oye Oba Oke - Ode

A fi woska wa yi kesi Saki Oba Ilorin ati awon Ijoye re gegebi oba wa na ti je Musulumi ti o si je eni - mimo - ti - Olorun wipe ki o fi oju anu re wo Ilu wa Oke - Ode Ile - Ire, nitoripe alafia ilu ni alafia awon enia inu re. Gbogbo awa omo ilu Oke-Ode Ile - Ire pelu awon Ijoye ilu ati awon af'obaje to wa nile, ati awon ti o wa ni Eko, Ibadan Ile - Ife ati awon ti o wa ni Oke - Okun ni a fi enu wa s'okan le ori Ogbeni Bello Lapinni Oyinloye gegebi eniti a fe ki o ro'po je oye oba ilu wa, Oke - Ode. - Ile Ire ti alagba oba wa Momodu Keye fi aye na sile nigbati o lo je ipe Olorun. BI KO BA NI IDI

Obiorin ko ni je kumo'lu, idi re ti a fi fe Ogbeni Bello Lapinni Oyinloye ni wipe baba to bi baba re ni oruko re nje Maku ti o te ilu wa Oke - Ode do baba ti o bi Bello papa ni oruko re nje Owuiani, o si je oye de ipo keta si oba Oke - Ode nigba aiye re ki ologo to de si i. Omo ti o wa mbe l'ori ile nisisiyi ni Bello Lapinni Oyinloye yi, ti o si je omoluwabi enia ninu oro siso, ninu iwa hihu ati ise re si enikeni, ojulowo omonure enia ni ise. Nitorina ni a se be oba wa Emir Ilorin ati awon Igbimo re wipe ki awon masai fi oju anu gba oran edun okan t'omode - t'agba ilu wa Oke - Ode yewo, ki nwon o si se iyonda fun wa gegebi ife okan wa ki a le ni alafia ati ilosiwaju rere nilu wa. Ki Allah fi emi gigun ti ola wa l'ore ati awon Ijoye re pelu alafia ara ki ilu Ilorin si ri agbega si, pelu ola Anabi Muhammadu. FATIYA

AWA NI OMO IBILE OKE — ODE

Gedegbe l'Eko wa
(O bere l'oju ewe keji)

ti o je wipe Alaiyeluwa Oba Adele Keji, Maja, ati Akanni Doherty ni e wa bere si lo yo lenu.

Nigbati a wi un nyin lape ki e tete fi epo oko o je aga, ti e wipe bowu epo ko o po u, ti e si je agatan ti epo toro ko kan u re, awon ti o ye ki e lo ba ni Ogbeni Mbadiwe, Kola Balogun H. O Davies

Etutu ti o mbe nibe ti okan yi ko fi ni se ni wipe ki e pa Eko po mo l'e Yoruba ki O'ola Awolowo le ri aye gba wa sile

Emi ni
Alawiye


**Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe**


Printed & Published by The Lagos Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370